# ÀMÌ ẸRANKO NAA

## Ifihan 13:1-18; 14:9-11

## ẸKỌ 462 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Gbogbo awọn ti ngbe ori ilẹ aiye yio si mã sin i, olukuluku ẹniti a kò kọ orukọ rẹ sinu iwe iyè Ọdọ-Agutan ti a ti pa lati ipilẹṣẹ aiye" (Ifihan 13:8).**

**I Ẹranko Naa**

1. Òkun naa lati inu eyi ti ẹranko naa ti jade wá n tọka si awọn eniyan, orilẹ ati ède, Ifihan 13:1; 17:15
2. Awọn ori meje naa ni ijọba meje, ekeje eyi ti iṣe ijọba ti ẹranko, tabi ti Aṣodisi-Kristi naa, Ifihan 13:1; 17:10, 11
3. Iwo mẹwaa naa ni awọn ọba mẹwaa ti wọn papọ labẹ ijọba Aṣodisi-Kristi, Ifihan 13:1; 17:12, 13
4. Eniyan ni ẹranko naa, o gba agbara rẹ lati ọdọ dragoni, tabi Satani, Ifihan 13:2; 20:2; 2 Tẹssalonika 2:3, 9

**II Ẹ̀sìn Buburu**

1. A ti ṣá ọ̀kan ninu awọn ori ẹranko naa pa, ṣugbọn ọgbẹ́ aṣapa naa ti jinná, Ifihan 13:3
2. Awọn eniyan n foribalẹ fun dragoni ati ẹranko naa, Ifihan 13:4, 8; 2 Tẹssalonika 2:4
3. Ẹranko miiran, tabi wolii eke dide, o n mú ki awọn eniyan fori balẹ fun ẹranko naa, Ifihan 13:11, 12; 19:20
4. Iṣẹ-iyanu pupọ ni a ṣe, a si ṣe aworan alaaye, eyi ti n sọrọ, ti wọn si n fori balẹ fún, Ifihan 13:13-15

**III Àmì**

1. Ẹranko naa sọ ọrọ-odi si Ọlọrun, Ifihan 13:5, 6
2. Ẹranko naa bá awọn eniyan mimọ́ jagun, Ifihan 13:7, 9, 10
3. Wolii eke naa mú ki gbogbo ẹni ti yoo ba rà tabi ti yoo ba tà, ki o gba àmì tabi orukọ tabi iye orukọ ẹranko naa, Ifihan 13:16, 17

**IV Ikilọ**

1. Iye ẹranko naa jẹ́ ọtalelẹgbẹta o le mẹfa, Ifihan 13:18
2. Ẹnikẹni ti o bá fori balẹ fun ẹranko naa, tabi ti o gba ami rẹ yoo ṣegbe laelae, Ifihan 14:9-11

## ALAYE

Ọpọlọpọ ni asọtẹlẹ ti o wà ninu Majẹmu Laelae ati Titun nipa ẹni irira kan, ti a n pè ni "ẹni ẹ̀ṣẹ," "ọmọ ègbé," ati "aṣodisi-Kristi." Gbogbo apele wọnyii n tọka si ẹnikan naa. Niwọn bi apejuwe "ẹranko" ti a darukọ rẹ ninu Ifihan 13 ti ba awọn asọtẹlẹ miiran ninu Bibeli mu, a mọ̀ pe itumọ ori iwe yii jẹ́ asọtẹlẹ nipa Aṣodisi-Kristi ati ijọba rẹ.

**Fifi Idi Ijọba Mulẹ**

Bi a ti n ka ti a si n ṣasaro nipa oriṣiriṣi orukọ ti a lò ninu Bibeli lati ṣe apejuwe Aṣodi-si-Kristi, eniyan le maa rò pe Aṣodisi-Kristi, yoo jẹ́ irira fun awọn eniyan ati pe yoo ṣoro fun un lati le jere ayé siha ti rẹ. Eyi ko ni ri bẹẹ nitori Aṣodisi-Kristi yoo gba ọna ti araye fẹran julọ: ipọnni, alaafia ati ọrọ̀. "Ni ipò rẹ li enia lasan kan yio dide, ẹniti nwọn ki yio fi ọlá ọba fun: ṣugbọn yio wá lojiji, yio si fi arekereke gbà ijọba. Yio si wọ̀ gbogbo ibi igberiko ọlọra; yio si ṣe ohun ti awọn baba rẹ kò ṣe ri, tabi awọn baba nla rẹ; yio si fọn ikogun ìfà, ati ọ̀pọlọpọ ọrọ̀ ká si ãrin wọn: yio si gbèro tẹlẹ si ilu olodi, ani titi akokò kan" (Daniẹli 11: 21, 24).

Ipọnni ati ohun iyọ̀ a maa yi ọkàn awọn eniyan pada - ani awọn ọkàn ti o ṣeeṣe ki o tilẹ lodi si iru nnkan bẹẹ patapata. Eyi ti ṣẹlẹ niye igba. Absalomu fi ipọnni yi ọkàn awọn eniyan Israẹli si ọdọ ara rẹ. Hẹrọdu sọrọ didùn fun awọn eniyan Tire on Sidoni ti o ti n binu gidigidi si, o si gbọ́ ti wọn wi pe "Ohùn ọlọrun ni, kì si iṣe ti enia" (Iṣe Awọn Apọsteli 12:22). Eniyan olohùn iyọ̀ jẹ́ alagbara, Aṣodisi-Kristi yoo si lo ohùn iyọ̀ rẹ lati mu ète rẹ ṣẹ, lati yi ọkàn awọn eniyan pada lodi si Ọlọrun dipo lati fa wọn sun mọ Ọn.

Alaafia jẹ ohun ti eniyan n ṣafẹri rẹ pupọ, ohunkohun ti yoo si gbà wọn ni wọn ti mura lati fi silẹ lati le ni in. A sọ fun ni pe iye awọn ọmọ Ẹgbẹ Ani-ohun-gbogbo-ṣọkan (Communist Party) kere pupọ laaarin ogunlọgọ

awọn eniyan Russia, awọn orilẹ-ede Europe ti o fara mọ Russia ati ogunlọgọ eniyan Red China. Sibẹ, awọn ogunlọgọ ti o pọ̀ ni ilẹ wọnyii gba awọn ẹgbẹ kekere wọnyii laye lati ṣakoso nitori ifarajọ alaafia ti o wà ninu ilu wọn ati ileri pe alaafia yoo pọ̀ si i fun wọn.

Igbe ayé lonii ni fun alaafia. Ija abẹlẹ jẹ́ ẹ̀ru, ewu ati aifọkanbalẹ igba gbogbo. Awọn eniyan n wá a ni gbogbo ọna, wọn si n lepa pẹlu gbogbo agbara ni ireti ati ri alaafia ti o daju. Aṣodisi-Kristi yoo ṣeleri alaafia ti yoo kari ayé. Ọrọ rẹ̀ ati alaye rẹ̀ yoo dabi ẹni pe o tọna, o si kun fun iyanu, fun igba diẹ alaafia yoo si wa. "Nigbati nwọn ba nwipe, alafia ati ailewu; nigbana ni iparun ojijì yio de sori wọn" (1 Tẹssalonika 5:3).

Ọrọ̀ yoo jẹ́ oofa miiran ti a o fi kún un ki awọn eniyan le fi ọlá fun Aṣodisi-Kristi. Ọrọ̀ ki maa n saaba mú eniyan di ẹni iwa-bi-Ọlọrun. Jesu wi pe, "Yio ti ṣoro to fun awọn ti o li ọrọ̀ lati wọ̀ ijọba Ọlọrun"! (Marku 10:23). Nigba pupọ ọrọ̀ jẹ́ ohun elo eṣu lati fa eniyan kuro lọdọ Ọlọrun, "Nitori ifẹ owo ni gbòngbo ohun buburu gbogbo" (1 Timoteu 6:10).

**Ọmọ Ọrun-Apaadi**

Lẹyin talẹnti rẹ̀ wọnyii ati awọn ohun nnkan ti ayé bi okunfa ti Aṣodisi-Kristi n lo lati fi fa awọn eniyan siha ti rẹ̀, o tun ni itilẹyin ti o ga ti o si lagbara ju eyi lọ -- "Dragoni na si fun u li agbara rẹ̀, ati itẹ rẹ̀, ati ọlá nla." Bibeli wipe, "Dragoni na, ejò atijọ nì, … ti iṣe Èṣu, ati Satani" (Ifihan 20:2). Johannu ri ẹranko, tabi Aṣodisi-Kristi yii, o ti inu òkun jade wá, eyi ti n tọka si ogunlọgọ eniyan. Ẹranko naa ni ori meje ati iwo mẹwaa, pẹlu ade lori awọn iwo naa ati orukọ ọrọ-odi ni awọn ori naa.

Bi Johannu ti n wò, ọkan ninu awọn ori rẹ̀ dabi ẹni pe a ṣa a pa. Ọrọ naa ni oòrìn pupọ, eyi ni pe ọgbẹ àpakù ni eyi. O gba iṣẹ-iyanu, eyi si ṣe ki ẹranko naa ba tun le wa laaye. Awọn akẹkọọ Bibeli kan ro pe lati inu ọrọ wọnyii, ati alaye rẹ̀: "Ẹranko … yio si ti inu ọgbun gòke wá, … ẹranko ti o ti wà, ti kò si sí mọ́, ti o si mbọ̀wá" (Ifihan 17:8). Aṣodisi-Kristi yii jẹ ọ̀kan ninu awọn onikupani awọn Onigbagbọ́ atijọ ti o tun pada bọ̀ si ayé. Boya ẹni ti o pada saye ni, tabi pe a dá ẹmi rẹ̀ pada nigba ti a pa a ni, wiwà laaye Aṣodisi-Kristi yoo di mimọ̀ fun gbogbo ayé. "Gbogbo aiye si fi iyanu tẹle ẹranko na."

Laiṣe àni-àni, ẹrọ amohun-mawòrán yoo jẹ́ ohun elo eṣu ni ọjọ naa (bi o ti n lo o nigbakuugba lonii) lati fi agbara rẹ̀ hàn ati lati kede iwa ibi rẹ̀ jake jado ayé. Nigba ti Amẹrika kọ́ gbé eniyan sinu awọsanma lati maa yi ayé po, a gbọ́ lati ibi pupọ pe awọn eniyan fi itara ọkàn wo nnkan naa ninu ẹrọ amohun-mawòran. Iroyin n tàn yi ayé ká ni iṣẹju ààyá. Ọna ati eto ati fi iroyin ranṣẹ n tẹ̀ siwaju lojoojumọ, nitori naa eṣu kò ni ni inira lati fi iṣẹ-iyanu rẹ̀ hàn agbaye.

Ẹranko naa yoo bori ayé patapata, ani ọmọ ọrun apaadi yi. Ayé yoo pọn ọn lé wọn yoo si juba rẹ, pe, "Tali o dabi ẹranko yi?" Ayé yoo mọ̀ pe kò ṣe anfaani lati fẹ dojukọ ipo ati aṣẹ rẹ̀, pe, "Tali o si le ba a jagun?" A ṣa a pa sibẹ o tun wà laaye. Ki ni ṣe ti a o tun fẹ́ pa a lẹẹkeji? O ni agbara ijinlẹ kan, ti o lẹru ju afọnja lọ. A o ha ṣe bi i ninu lati pa araye run? Ki wọn le wà laaye, awọn eniyan yoo maa ṣiṣẹ fun un, wọn o si maa ṣiṣẹ pẹlu rẹ̀.

**Agbára Isin**

Iwe Mimọ́ n kilọ pe awọn eniyan yoo foribalẹ fun Aṣodisi-Kristi, ati bakan naa fun dragoni ti o fun un ni agbara, itẹ́ ati ọlá. A ti maa n gbọ́ nipa sisin eṣu ni ayé yii, ṣugbọn kiki ni igba okunkun ayé atijọ ni, ni agbegbe awọn orilẹ-ède alaimọkan. Ṣugbọn gbogbo eniyan, ayafi kiki awọn ti a ti kọ orukọ wọn sinu Iwe Iye, ni yoo sin ti wọn yoo si fi ori balẹ fun dragoni ati Aṣodisi-Kristi. Bawo ni eyi ṣe le ri bẹẹ? A fun ni ni idahun rẹ̀ ninu 2 Tẹssalonika 2:3, 4, 8-12. Iyapa buburu kuro ninu awọn ipilẹṣẹ otitọ ọrọ Kristi Jesu ti dé, nipasẹ Ẹsin igbalode, ẹkọ nipa iṣẹda ayé, awọn ẹkọ eke, ati bẹẹ bẹẹ lọ. A o fi Ẹni ẹ̀ṣẹ ni hàn "ẹniti wíwa rẹ̀ yio ri gẹgẹbi iṣẹ Satani pẹlu agbara gbogbo, ati àmi ati iṣẹ-iyanu eke, ati pẹlu itanjẹ aiṣododo gbogbo." Nitori ti awọn eniyan ko fẹ otitọ, wọn o gba eke yii gbọ́ wọn o si jẹbi, awọn ti ko gba otitọ gbọ́ ṣugbọn ti wọn ni inudidun ninu aiṣododo. O ti ṣe danindanin to lati gba ifẹ otitọ Ọlọrun! O ti nilaari to lati sin Jesu Kristi lonii nigba ti akoko ati anfaani wà! Ọrọ Ọlọrun ni lati kilọ fun ẹlẹṣẹ lati sá asala kuro ninu ibinu ti n bọ̀ -- lati sá là sinu abo ti ti ó wà ninu Ẹjẹ Jesu Kristi.

Ẹranko miiran tun fara hàn, jẹ́jẹ ni irisi, o ni iwo meji bi ti ọdọ-agutan. Ibi wo ni eniyan ti o dabi ọdọ-agutan le ṣe? Jesu kilọ nipa awọn wolii eke ti yoo wá ninu àwọ agutan. Ẹranko ti o ni iwo meji yii ni wolii eke ti a sọrọ rẹ̀ ninu Ifihan 19:20. O n sọrọ bi dragoni, nitori naa ko yẹ ki o ṣoro fun eniyan lati mọ orisun agbara rẹ̀.

Wolii eke naa gba iṣakoso patapata lori nnkan naa ti o wà ninu ọkàn eniyan ti n mu un lati fẹ jọsin. Ẹranko ekini, eyi ti ọgbẹ aṣapa rẹ̀ ti san, ni ohun ti wọn n foribalẹ fún. Ajinde Jesu Kristi kuro ninu oku ti jẹ́ ẹri ti o

daju nipa eto Ọlọrun fun igbala araye; nitori naa eṣu n dari awọn eniyan sinu egbe ti o daju nipa ṣiṣe iṣẹ-iyanu ti o fara jọ ọ́. Aṣodisi-Kristi ti ipò oku jade wá! Iṣẹ iyanu wo ni o ga ju eyi lọ? Wolii eke naa mu eyi lò, nitori naa o mu ki awọn ti n gbe orilẹ ayé fori balẹ fun Aṣodisi-Kristi.

Lati fi agbara hàn si i, wolii eke naa pe iná sọkalẹ lati ọrun wá loju awọn eniyan. Nigba ti awọn eniyan Israẹli ri ti iná bọ́ sori ẹbọ Elijah, wọn ké pe, "OLUWA, on li Ọlọrun." Ni igba wolii eke naa, awọn eniyan yoo fi aitọ́ gba iṣẹ iyanu bẹẹ ni ẹri ti o fi titọ ẹkọ wolii eke naa hàn.

**Àmi**

Eṣu mọ̀ o si ti n fi igba gbogbo gbiyanju lati rú ìfẹ ọkàn awọn eniyan soke lati fẹ ni ati lati fẹ lo ohun ti a le fi oju ri ninu ijọsin wọn, bi o tilẹ jẹ pe Ọlọrun kọ eyi. Eṣu yoo lo ifẹ ọkàn eniyan yii de ogogoro ni igba ayé ikẹyin yii, yoo si mu ki wolii eke naa daba ati yá aworan ẹranko naa ti ọgbẹ aṣapa rẹ̀ ti san. Wolii eke naa ni agbara lati fi eemi fun aworan naa de ibi pe aworan naa n sọrọ yoo si mu ki a pa gbogbo awọn ti ko fori balẹ fun aworan naa.

Eṣu kò ni itẹlọrun lori kiki pe ki awọn eniyan fori balẹ fun oun ati awọn iranṣẹ rẹ̀; yoo fi ootẹ tabi àmi rẹ̀ si wọn lara. Aṣodisi-kristi yoo gba agbara ati akoso ayé nipa ti ijọba ati ẹsìn. Ni akoko yii wolii eke yoo mú ki gbogbo eniyan, ati kekere ati nla, ọlọrọ ati talaka, ominira ati ẹru, gba ami kan. Awọn eniyan naa le yàn: ami ti o dabi eyi ti kò ṣe pataki, tabi orukọ ẹranko naa, tabi iye orukọ rẹ̀. Bi eniyan ko ba fẹ ami naa ni gbangba iwaju rẹ, o le gba ami naa si ọwọ́ ọtun rẹ̀. A kò fun wọn lati yàn yala lati gba ami naa tabi lati kọ̀ ọ́: ẹnikẹni ti yoo ba rà tabi ti yoo tà lọjọ naa ni lati ni ami ẹranko naa -- ootẹ eṣu.

**Akoko Ti Kọja**

Ẹṣẹ maa n fi ami rẹ sara ọkàn ati ayé eniyan, ṣugbọn Ọlọrun le pa ami naa rẹ́ nipasẹ Ẹjẹ iyebiye ti Jesu Kristi nigba ti eniyan ba ronupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ̀. Ṣugbọn ami ẹranko naa ko le ṣe e parẹ lọnakọna, lẹẹkan ti a ba ti gba a. Yoo sàn ki eniyan sọ ẹmi rẹ̀ nù li ọjọ naa jù fún un lati gba ami ẹranko naa. "Bi ẹnikẹni ba nforibalẹ fun ẹranko nì, ati aworan rẹ̀, ti o si gbà àmi si iwaju rẹ̀ tabi si ọwọ́- rẹ̀, on pẹlu yio mu ninu ọti-waini ibinu Ọlọrun, ti a tú jade li aini àbula sinu ago irunu rẹ̀; a o si fi iná ati sulfuru da a loró niwaju awọn angẹli mimọ́, ati niwaju Ọdọ-Agutan: ẽfin oró wọn si nlọ soke titi lailai, nwọn kò si ni isimi li ọsán ati li oru, awọn ti nforibalẹ fun ẹranko na ati fun aworan rẹ̀, ati ẹnikẹni ti o ba si gbà àmi orukọ rẹ̀" (Ifihan 14:9-11).

**Sisala**

Ọlọrun ti pese ọna ati sala kuro ninu akoko ipọnju yii ati ohun ti yoo tẹle e ni ayeraye. Jesu tun n pada bọ̀ sori ayé lati mu awọn eniyan mimọ́ aṣẹgun lọ ki a to fi Aṣodisi-Kristi hàn ninu ijọba blasfemi rẹ̀. Ọlọrun ti na ọwọ́ ipe jade si gbogbo eniyan fun igbala. A n gbé ni akoko ewu, o si yẹ lati ta ọkàn awọn eniyan jí ki iparun ojiji yii to de sori wọn. Ki Ọlọrun ran olukuluku ọkàn lọwọ lati mu anfaani iyebiye yii lo ati lati ba A laja lonii!

"Njẹ ki ẹ mã ṣọna, ki ẹ si mã gbadura nigbagbogbo, ki ẹ ba le là gbogbo nkan wọnyi ti mbọ̀ wá iṣẹ, ki ẹ si le duro niwaju Ọmọ-enia" (Luku 21:36).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni orukọ miiran fun ẹranko naa? Fun dragoni naa?
2. Ki ni ṣe ti ayé yoo maa fi iyanu tẹle ẹranko naa?
3. Ta ni awọn eniyan yoo maa fori balẹ fun ni ọjọ naa?
4. Yoo ti pẹ́ to ti ẹranko yii yoo fi wà?
5. Awọn ta ni ẹranko naa yoo jọba lé lori?
6. Ki ni wolii eke naa yoo ṣe?
7. Lọna wo ni eṣu yoo fi sami sara awọn ti n sin in?
8. Awọn wo ni yoo gba ami ẹranko naa?
9. Ki ni yoo jẹ́ opin awọn ti o bá gba ami ẹranko naa?